# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸLẸ

## ỌKÙNRIN TI ẸGBẸ̀RÚN ỌDÚN NÁÀ

## Ìtàn ...

**Danieli 2:1-49**

Ijọba Babiloni jẹ́ ijọba nlá tó sì ni ọrọ̀ púpọ̀púpọ̀, síbẹ̀ Nebukadnessari ọba tún n dààmú lori ibùsùn ọba rẹ̀. Ó wòye pé, bawo ni ìgbà oun yio ṣe gùn tó, ati pé kini yio ṣẹlẹ̀ si ijọba alágbára oun nígbà tí oun bá kú tán?

Pẹlu ìbéèrè tó n dààmú ọkan rẹ̀, lorí èrò yí ni atẹ́gùn ti fẹ́ sí i, ti ọba sì rọra sùn lọ. Ní òru ọjọ́ náà ni ó lá àlá, tí ó sì rí ère, tí dídán rẹ̀ ndán gidigidi, irú èyí tí kò iti rí rí.

Lẹ́hìn tí ọba ti sí aṣọ-ìbora kúrò ni ara rẹ̀, o sáré dide kúrò lorí ibùsun rẹ̀, o si pariwo sí awọn ìránṣẹ rẹ̀ pé: "ki a pe àwọn amòye àti ọlọgbọ́n wá ní kíá. Mo gbọdọ̀ mọ ìtumọ̀ àlá yi!"



Lógán gbogbo awọn ọlọ́gbọ́n ti dúró níwájú ọba tí ọkàn rẹ̀ ti dàrú yí. "Ọba sì wí fun wọn pé, mo lá àlá kan, ọkàn mi kò sì le ilẹ̀ lati mọ̀ àlá naa." Danielii ẹ̀:é. Ọ̀kan ninu awọn woli èké naa dahun pé, "Rọ́ àlá naa fun awọn ọmọ-ọ̀dọ̀ rẹ̀, àwa o si fi itumọ̀ naa hàn." Gẹ́gẹ́ bi o ti ma nṣẹlẹ̀ sí awọn àlá, Nebukadnessari kò rántí àlà náà mọ́. Awọn ọkunrin wọnyi ti ma n ríran tẹ́lẹ̀, níbayi, ọba ti bẹ̀rẹ̀ sí í siyèmejì lorí agbara wọn. Eleyí yio jẹ àyẹ̀wò pípé. Ọba sọ fún awọn olùgbani-ní-mọ̀ràn naa pé "ẹ sọ àlá naa fun mi ati ìtumọ̀ rẹ̀', emi yio sì fi ọrẹ fun nyin, bikose bẹ́ẹ̀, a o ké nyin sí wẹ́wẹ́, a o si sọ ilé nyin di ààtàn!"

AMAZING FACTS

Awọn amòye ati awọn ọlọ́gbọ́n gbọ́dọ̀ gbà pé, awọn kò lagbara lati tumọ̀ àlá ọba bikoṣepé wọn kọ́kọ́ gbọ́ bi ọba ṣe lá àlá naa. Ọba bínú gidigidi sí awọn èké wọnyi, ọba paṣẹ pé kí nwọn ki o pa gbogbo awọn amoye Babeli run. Síbẹ̀, Ọlọrun tì ní ẹnikan ni Babiloni ti o le ṣàlàyé àlá ọkùnrin ti ijọba rẹ̀ gbòòrò ti iṣe ti ìjọba ẹgbẹ̀rún ọdún yi.

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọnyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọọkan tán.

**1. Kíni ìdí ti Ọlọrun fi fun ọba Babiloni ní irú àlá bi èyí?**

**Danieli 2:28**

Ṣùgbọ́n Ọlọrun kan mbẹ li ọrun ti o nfi ________ hàn, ẹniti o si fi hàn fun Nebukadnessari ohun ti mbọ̀ wá ṣẹ ni _________ ọjọ́. Àlá rẹ, ati iran orí rẹ lori akete rẹ, ni wọnyí.

Àkíyèsí: Nínu àlá yi, ti iṣe ti ère oniruuru àwọ̀, Ọlọrun sàlàyé fun wa lori ijọba ẹgbẹ̀run ọdun tí yio dìde, ti yio sì subú, tí yio ṣe ni ipá lori awọn eniyan Rẹ̀ (Ọlọrun).

**2. Nígbàtí awọn ìgbìmọ̀ ọba kò le è fi ìtumọ̀ àlá rẹ̀ hàn fun un, àṣẹ wo ni Nebukadnessari pa?**

**Danieli 2:12**

Nitori ọ̀ràn yi ni inú ọba fi bàjẹ́, o si binu gidigidi, o si paṣẹ pé ki nwọn ki o ________ gbogbo awọn amoye Babeli run.

Àkíyèsí: Awọn amòye ati awọn ọlọ́gbọ́n ilẹ̀ Babiloni ma nsọ pe awọn ni agbara nlá, ṣùgbọ́n nígbàtí wọn kò le è fi àlá ọba hàn, a ri wọn gẹ́gẹ́ bi alailagbara, ti wọn si tún jẹ́ ẹlẹ̀tàn. Bí o bá ṣepé, ọba ti rọ̀ àlá rẹ fun wọn ni, wọn ìbá ti wá ìtumọ̀ kan sá á lati ṣe ìtumọ̀ rẹ̀. Ninu ibinú rẹ̀, Nebukadnessari paṣẹ ki wọn pa gbogbo awọn ọlọ́gbọ́n - títí de orí awọn tí kò sí nibẹ̀. Lara awọn tí kò sí ninu ìpàdé àkọ́kọ́, ni ẹnìkan ti o bẹ̀rù Ọlọrun ti iṣe ìgbèkùn ti orukọ rẹ̀ njẹ́ Danieli, ẹniti a ṣẹ̀ṣẹ̀ kọ́ ní siṣe ìrànṣẹ fun ọba.

**3. Nígbàtí Danieli gbọ́ àṣẹ ikú náà, kini Danieli bi ọba léèrè ati pé kilo sọ fun awọn ọ̀rẹ́ rẹ̀?**

**A. Danieli 2:16**

Nigba naa ni Danieli wọlé lọ, o si bèrè lọwọ ọba pe, ki o fi _________ fun oun, o si wipé, oun ó fi ìtumọ rẹ̀ hàn fun ọba.

**B. Danieli 2:17,18**

Nigba naa ni Danieli lọ si ilé rẹ̀, o si fi nkan naa _________ fún Hananiah, Miṣaeli, ati Asariah, awọn ẹgbẹ́ rẹ̀: Pé, ki nwọn ki o bèrè aanu lọ́wọ́ Ọlọrun, Oluwa ọrun, nitori _________ yi: ki Danieli ati awọn ẹgbẹ́ rẹ̀ má ba ṣègbé pẹlu awọn ọlọgbọ́n Babeli iyoku, ti ó wà ni Babeli.

Àkíyèsí: Danieli bèèrè fun àkókò díẹ̀ lọ́wọ́ Nebukadnessari, ó sì sèlérí lati fi àlá naa hàn pẹlu itumọ rẹ̀. Ọba tó jẹ pé ẹ̀rù si nbà, tí ó si fẹ́ mọ ìtumọ̀ ìran rẹ̀, o fun Danieli ni ibèrè rẹ̀. Lẹ́hìn náà ni oun ati ọ̀rẹ́ rẹ̀ lọ si Orisun kan soso ti o le fi àlá ọba hàn. Wọn gbadura si Ọlọrun ọ̀run.

**4. Nígbàtí Oluwa fi àlá náà hàn fun Danieli, tani ó fi ìyìn ati èyẹ fún?**

**Danieli 2:23,28**

Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ, mo si fi ìyìn fun ọ, Iwọ_________ awọn baba mi, ẹniti o fi ọgbọ́n ati agbára fun mi, ti o si fi ohun ti awa bèrè lọ́wọ́ rẹ hàn fun mi nisinsinyi: nitori ti iwọ fi ọ̀ran ọba hàn fun wa nisinsinyi, Ṣùgbọ́n _________ kan mbẹ li ọ̀run ti o nfi àṣírí _________, ẹnití o si fi hàn fun Nebukadnessari ohun ti mbọ̀ wá ṣẹ ni ikẹhìn ọjọ́. Àlá rẹ, ati ìran rẹ lori akete rẹ, ni wọnyi.

Àkíyèsí: Ìdìde ati iṣubú awọn ijọba le è dabi ìfẹ́ eniyàn, ṣùgbọ́n àdúrà Danieli ti fi pàtàki dídásí lati ọ̀run hàn. Kò sí ohun to sẹlẹ̀ tí ó jẹ́ wípé Ọlọrun kò mọ̀ nípa rẹ ati pé Ọlọrun tún gbà á láàyè. Ní ẹkọọkan, a lè ma mọ ohun to nṣẹlẹ̀ ninu ayé loni ati ìdí rẹ, ṣùgbọ́n ìtùnú wa ni lati mọ̀ pé Ọlọrun si njọba. Danieli nìkan lo le e fi àlá ọba hàn, síbẹ̀, o fi èyẹ fun Ẹniti o fi àlá náà hàn fun un ni gbangba - ti iṣe Ọlọrun ọ̀run.

**5. Kini ohun meji ti Danieli sọ wípé ọba rí ninu àlá rẹ?**

**A. Danieli 2:31**

Iwọ ọba nwò, sì kíyèsí, _________ _________ kan. Ère gíga yi, ti didán rẹ̀ pọ̀ gidigidi, o dúró niwaju rẹ, ìrí rẹ̀ si ba ni lẹ́rù gidigidi.

**B. Danieli 2:34**

Iwọ ri títí _________ kan fi wá láìsí ọwọ́, o si kọlu ère naa lẹ́sẹ̀ rẹ̀, ti iṣe ti irin ati amọ̀, o sì fọ́ wọn túútú.

Àkíyèsí: Ohun àkọ́kọ́ tí ọba ri ni ère nlá kan ti a fi oniruurú èlò wọnyi lati inú ilẹ̀ mọ:

1. Orí rẹ̀ jẹ́ wúrà.
2. Àyà ati apá rẹ̀ jẹ́ fàdákà.
3. Inú ati itan rẹ̀ jẹ́ idẹ.
4. Ẹsẹ̀ rẹ̀ jẹ́ irin.
5. Atẹlẹsẹ̀ rẹ̀ jẹ́ irin ati amọ̀.

Lẹhìn èyí, ọba ri òkúta kan tí ó wá láìsí ọwọ́. Ní ikorita yi, ẹ̀rù ti ba ọba Nebukadnessari débi pé, ó fẹrẹ jabọ lórí ìtẹ́ ti ó joko le lórí. Danieli ti sọ gbogbo bi àlá naa ti ri gẹ́gẹ́ bi Ọlọrun ti fi hàn án. Níbayi, ọba nduro titatira lati mọ ìtumọ̀ àlá naa. Danieli naa tẹsíwájú lati sàlàyé itumọ̀ àlá naa gẹ́gẹ́ bi Oluwa ti fi hàn fun un, ohun tó dára ni pé kí a gba àlá náà gẹ́gẹ́ bi Ọlọrun ṣe fi funni. Ọ̀nà kan to dára jù lati túmọ̀ Bibeli ati ìsọtẹlẹ ni pé ki a jẹ ki Bibeli túmọ̀ ara rẹ̀.

**6. Kíni ori wúrà dúró fún?**

**Danieli 2:38**

Ati nibikibi tí ọmọ eniyan wà, ẹranko ìgbẹ́ ati ẹyẹ ojú-ọ̀run li o si fi le ọ lọwọ, o si ti fi ọ se alakoso lori gbogbo wọn. Iwọ li _________ wúrà yi.

Àkíyèsí: A npe ọba ni olórí ìpínlẹ̀. Ìdí niyi ti Nebukadnessari fi dúró fun Babiloni, ijọba tó bẹ̀rẹ̀ isọtẹlẹ. Neo-Babiloni sàkóso ayé lati ọdun 612 sí 539 B.C. gẹ́gẹ́ bi ijọba tó lagbara jù ni àtijọ́ - ẹnití a lè júwe bí i orí wúrà náà. Kíyèsi pé, asọtẹlẹ bẹ̀rẹ̀ ni àkókò ti Danieli.

**7. Ṣé ìjọba Babiloni yio dúró títí lailai bí?**

**Danieli 2:39**

Lẹhin rẹ ni ijọba _________ yio si dide ti yio rẹ̀hin jù ọ, ati ijọba kẹta miran ti iṣe ti idẹ, ti yio si se alakoso lori gbogbo ayé.

Àkíyèsí: Ìjọba Babiloni ki yio wà títí lái. Ijọba miran yio gba ipò lọ́wọ́ Babiloni, ti iṣe ìjọba kékeré, oun ni yio sàkóso. Gẹ́gẹ́ bi fàdákà ṣe kéré si wúrà, bẹ́ẹ̀ ni ògo ìjọba tó tẹle Babiloni yio kéré. A dari ìjọba náà nipaṣẹ̀ Kirusi ni ọdún 539 B.C., ìjọba Medo-Persian borí Babiloni, o si pa á run. Agbara to njọba lorí ayé ni ọdun 539 sí 331 B.C. ni Medes ati Persians. Nígbàtí wọn njọba, ti awọn eniyan ba fẹ́ san owó orí, fàdákà ni wọn fi n san án.



YOR-SP1.indd 1
12/6/12 9:41 AM

**8.** Irú irin wo ni yio dúró fun ìjọba tí yio tẹle Medo-Persia?
**Danieli 2:39**
Lẹhin rẹ ni ijọba miran yio si dide ti yio rẹhin jù ọ, ati ijọba kẹta miran ti iṣe ti _________, ti yio si ṣe alakoso lori gbogbo ayé.

Àkíyèsí: Ìjọba idẹ ti Greece gun orí àga ìjọba nígbàtí Alexander the Great ṣẹgun Medes ati Persians nibi ogun Arbela ni ọdún 331 B.C., ìjọba Greece si tẹsiwajú titi di ọdún 168 B.C. A ma npe awọn ọmọ-ogun Griki ni “brazen coated” nítoripe bronze ni a fi ṣe ihámọra wọn. Fiyesi bi awọn irin naa se ndinkù ninu iye orí wọn lára ère naa, síbẹ̀, ọdun ikini gùn ju ekeji lọ.

**9.** Irin wo lo dúró fun ìjọba kẹrin?
**Danieli 2:40**
Ijọba kẹrin yio si le bi _________; gẹgẹ bi irin ti ifọ tuutu, ti si iṣẹgun ohun gbogbo ati gẹ́gẹ́ bi irin naa ti o fọ gbogbo wọnyi.

Àkíyèsí: Ìjọba Romu tó jẹ́ irin ló ṣẹgun Griki ni ọdun 168 B.C. o sì gbàdun agbára nlá rẹ titi di ìgbà tí a di Romu ni ìgbèkùn nipasẹ Ostrogoths ni ọdun A.D. 476. Romu ni ijọba to njọba lori gbogbo ayé nígbàtí a bí Jesu. Wo bi Danieli ṣe sọ asọtẹlẹ lori ìtàn àgbáyé ni ìwọn ẹgbẹrun ọdun sẹ́hìn ti o si jẹ́ òtítọ́ síbẹ̀. Idide ati iṣubú ìjọba mẹrẹrin wọnyi - Babiloni, Medo-Persia, Greece, ati Romu, ni a ti sọ di mímọ̀ ninu Bibeli, ti a si jẹri rẹ pẹlu awọn ìwé ìtàn.

**10.** Kini yio tún sẹlẹ̀ lẹhìn iṣubú ìjọba Romu?
**Danieli 2:41,42**
Ati gẹ́gẹ́ bi iwọ ti ri ẹsẹ̀ ati ọmọkasẹ̀ ti o jẹ apakan amọ̀ amọkoko, ati apakan irin, ni ijọba naa yio _________ si ara rẹ; ṣugbọn ipá ti irin yio wà ninu rẹ, niwọn bi iwọ ti ri irin ti o dapọ mọ amọ̀, Gẹ́gẹ́ bi ọmọkasẹ naa ti jẹ apakan irin ati apakan amọ̀, bẹ̃li apakan ìjọba naa yio lagbara, apakan yio si jẹ́ ohun fifọ.

Àkíyèsí: Nígbàtí ìjọba Romu bẹ̀rẹ̀ si idàrú ni ọdún A.D. 476, ìjọba miran gba agbára lori ayé. Dípò èyí, awọn ẹ̀yà barbarian borí ìjọba Romu, wọn si pín in gẹ́gẹ́ bi Danieli ṣe sọtẹlẹ̀. Mẹwa ninu awọn ẹ̀yà naa lo di Europe. Awọn ni Ostrogoths, Visigoths, Franks, Vandals, Alemannians, Sueves, Anglo-Saxons, Heruls, Lombards, ati Burgundians. Ẹ̀yà meje ninu wọn sì wà ni Europe loni. Fun àpẹrẹ, Anglo-Saxons di English, Franks di French, Alemannians naa di Germans ati Lombards náà di Italians.

**11.** Njẹ́ awọn ìjọba mẹwẹwa yi yíò ṣe aṣeyọri ni sísọ̀kan bí?
**Danieli 2:43**
Ati gẹ́gẹ́ bi iwọ si ti ri irin ti o dapọ mọ amọ̀, nwọn o dá ara wọn pọ mọ irú-ọmọ eniyan, ṣugbọn nwọn kì yio fi _________ wọn mọ ara wọn, gẹ́gẹ́ bi irin kì ti idapọ mọ amọ̀.

Àkíyèsí: Nípasẹ̀ igbeyàwó, ẹgbẹ́ ati ìtọ́jú, awọn eniyan ti gbiyanjú lọ́pọ̀lọpọ̀ lati so awọn agbègbè tó wà ni Europe papọ̀. Ninú gbogbo ìtàn awọn olórí bí i Charlemagne, Napoleon, Kaiser Wilhelm, Mussolini, ati Hitler ti sakitiyan láti gbé ìjọba Europe titun dìde; ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ Ọlọrun wọ̀nyí ti dá gbogbo ìgbìyànjú ìjọba kan soso ní àgbáyé dúró. Ifihan 13 sọ fun wa pé, akitiyan lati dá ẹ̀sìn kan silẹ̀ ni gbogbo ayé yio wáyé, ṣùgbọ́n asọtẹlẹ Danieli ti fi ye wa pé gbogbo ayé yio pín yẹlẹyẹlẹ titi dé òpin ni.



**12.** Tani yio gbé ìjọba ikẹhìn dìde?
**Danieli 2:44**
Li ọjọ awọn ọba wọnyi li _________ _________ yio gbé ijọba kan kalẹ, eyi ti a ki yio le parun titi lai: a kì yio si fi ìjọba naa le orilẹ-èdè miran lọ́wọ́, yio si fọ́ tútú, yio si pa gbogbo ijọba wọnyi run, ṣùgbọ́n oun o dúró títí lailai.

Àkíyèsí: Ìjọba gbogbo ayé ti yio tún wà ni ti ìjọba ọ̀run, èyí ti a sàpejuwe ninu Matteu 25:31-34.

**13.** Kini òkúta náà ṣe sí awọn ìjọba àgbáyé miran?
**Danieli 2:34,35**
Iwọ ri títí òkúta kan fi wá laisi ọwọ́, o sì _________ ère naa lẹsẹ rẹ, ti iṣe ti irin ati amọ̀, o si _________ wọn túútú, Nigbà naa li a si fọ irin, amọ̀, idẹ, fàdáká ati wúrà pọ̀ túútú, o si dàbí ìyàngbò ipaka nigbà ẹ̀rùn; afẹ́fẹ́ si gba wọn lọ, ti a kò si ri ibi kan fun wọn mọ́: okuta ti o si fọ ère naa si di _________ nlá, o si kún gbogbo ayé.

Àkíyèsí: Òkúta náà ti o fi wá láìsí ọwọ́ dúró fún ìjọba Ọlọrun. Ìjọba náà kì yio jẹ́ ti ọ̀pọ̀lọpọ̀ awọn ìjọba ti ayé, ṣùgbọ́n yio jẹ ìpàárọ̀ pátápátá (Ifihan 21:1). Ìwe mímọ́ là á yé wa pé nígbàtí Jesu Kristi bá padà dé sinú ayé, yi O pa gbogbo ìjọba ayé run, yi O si gbé ìjọba ayéraye kalẹ̀ (Danieli 2:44). Irú ìròhìn nlá wo lèyí! Jesu nbọ̀ padà wá! Gbogbo ìtàn ti nlọ sí òpin, nígbàtí Ọmọ Ọlọrun yio padà wá ninu ọlá nlá Rẹ, lati mu ìjọba òdodo àìnípẹkun wá. Ọba Nebukadnessari rò pé oun ti borí Ọlọrun òtítọ́ nígbàtí oun ti dó ti Jerusalemu ti ó si ti kó awọn ohun-èlò tó wà ninu tẹmpili lọ (Danieli 1:1,2), ṣùgbọ́n a fi hàn án ní kánkán wípé Ọlọrun ni aláṣẹ lorí ohun gbogbo. Ohun gbogbo ti eniyan nse ló wà ni abẹ́ ìsàkóso Rẹ, nitori náà Ọlọrun yi O borí ogun náà. Babiloni Medo-Persia, Greece, Rome, ati ìpín mẹwa ti ìjọba Romu ni wọn ti gbìyànjú lati gba àṣẹ àtọrun wá pẹlu agbára ati lati pa awọn eniyan Ọlọrun run, ṣùgbọ́n gbogbo ìjọba ayé ni a o parun nígbàtí Kristi bá dé. Ọpẹ́ ni fun Ọlọrun, yi O borí àríyànjiyàn nlá!

**14.** Lẹ́hìn ìgbàtí o ti gbọ́ ìtumọ̀ àlá náà, kíni Nebukadnessari sọ nipa Oluwa?
**Danieli 2:47**
Ọba dá Danieli lohùn, o si wípé, Lootọ ni, pe Ọlọrun nyin li _________ awọn _________ ati Oluwa awọn ọba, ati olùfihàn gbogbo àṣírí, nitorí ti ìwọ le fi àṣírí yi hàn.

Àkíyèsí: Nígbàtí ó ti ri i pé Ọlọrun ni aláṣẹ pátápátá lori gbogbo àgbáyé, Nebukadnessari pẹlu naa mọ̀ pé Ọlọrun tí Danieli nsìn jẹ́ olórí lori gbogbo awọn ọlọrun tó wà ni Babiloni. Báwo ni áwòrán náà se tètè yipadà! A gbé Danieli ati awọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ ga lati inu ìgbèkùn si ipò alaṣẹ fun awọn igberiko, nitori òtítọ́ wọn sí Ọlọrun (Danieli 48,49). Ọlọrun ma nbọlá fun awọn tó bá bọlá fun un (1 Samueli 2:30).

# Èsì Rẹ

Bí o bá mọ̀ pé Ọlọrun ni alákoso lori ohun gbogbo láyé, ṣe o fẹ́ ki o gbàkóso lori ayé rẹ náà?

ÌDÁHÙN: _______________



# Àfikún

Ipele yìí yio fun wa ni awọn ọ̀rọ̀ afikun lati tun mu wa kẹkọ síwájú si.

Wúrà = Babiloni
Orí wúrà dúró fun Babiloni, èyí ti iṣe agbára to sàkóso ni ọdun 612 tító di 539 B.C.

Fàdákà = Medo-Persia
Àyà fàdájà dúró fún Medo-Persia, ìjọba tó sàkóso ni 539 sí 331 B.C.

Idẹ = Greece
Itan idẹ dúró fún Greece, ìjọba tó fagbára sàkóso ni 331 sí 168 B.C.

Irin = Romu
Ẹsẹ irin dúró fún Romu, ti ó gbádùn agbára lati 168 B.C. títí di A.D. 476.

Irin ati amọ̀ = ìjọba tó pín
Atẹlẹsẹ̀ tó jẹ́ apakan irin ati apákan amọ̀ dúró ìjọba tó ti pín tí kì yio sopọ̀ padà. Kò sí agbára kankan to sàkóso mọ́ lati A.D. 476, yio si wà ní pínpín títí di ìgbà ti Kristi yio fi padà wá.

Òkúta = Ìjọba Ayéraye ti Kristi, Ọ̀rọ̀ Rẹ, ati Òfin Rẹ.



© Review and Herald

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP1.indd 2 12/6/12 9:41 AM